# EKO AKETE.

"EMI YIO FI OHUN TI O NDUN MAKUNNU HAN AWON ALAGBARA, NGO SI JE ALAGBAWI AWON ODI."—W. T. STEAD.

VOL. III. No. 115 SATURDAY, SEPT. 27, 1924. FOURPENCE.

**DURO THOMAS.**

55, MASSEY STREET, LAGOS, (NIGERIA.)

P.O. Box 374. Telephone No. 243.

*The Best House for every Description of German Goods.*

**"Specialities: Enamelware Beer, Wine, Iron Bedsteads, Ruby Plates, Rubber Beads of all kinds, Clay and Briar Pipes, Champagne, Cement, Biscuits in cases, Gun Powder, Wire Nails Raugoon and original Ballam Rice, Accordeons, Piano, Padlocks, Beads, etc., etc., etc."**

30 SEP 1924

**N. V. HANDLEMATTSCHAPPIJ V.H.**

OYINBO **J. F. SICK**

Ọba Ilẹkẹ, Ile Ilẹkẹ, 9, Ita 'Bode lailai, Eko.

A jẹ Ajirera ninu òwò Ilẹkẹ, orișirișị Ilẹkẹ wọnyi wa ni tita:—

Ilẹkẹ Oyinbo, Ilẹkẹ Rubber, Ilẹkẹ Olomi Wajì, Ilẹkẹ Onikẹkẹ, Ilẹkẹ Elejo, Ilẹkẹ Ayinrin, Ilẹkẹ Oniwõrò ati Fadaka, Ilẹkẹ Kerewu, Ilẹkẹ Jòjò, Ilẹkẹ Òlokuta, Ilẹkẹ Oloruka, Ilẹkẹ Ẹlẹranko, Ilẹkẹ didan Yinrinyinrin, Ilẹkẹ Meremere, Ilẹkẹ Mọjọkun, Ilẹkẹ Adumãdan.

Ẹ wa wo Ile ọja wa; A ni nkan wọny fun tita:—

Ikoko taba Onigi, Jigi, Aṣọ Aran, Ẹrọ agbado, Ife, Ọti Elewuro (*Beer*) ati Eleso Àjàrà (*Wine*), Awọn onjẹ Ipamı, aṣọ iș'ọṣọ, Ẹrọ ere ọmọde, Ohun Ọṣọ, Abẹlà (*Candles*) ati ẹgbagbeje ọja miran.

A nta Mașini *Vesta*, a si ni *Cement* atata ti Portland ati irin pipọn abẹ oni *Diamond*. Idi òwò wa wa ni Rotterdam, a si ni Ile owo ni:— Calabar, Gablonz (Czecko-Slovakia) Gold Coast, Accra, Lome Hamburg, London, Venice (Italy).

# LEVER STORES LTD.

## No. 1, LAGOS.

# OLOWO S'OKE D'ILẸ

A ni oriṣiriṣi ọja fun tita ni owo ọpọku-ọyọku.

A nta awọn ọja wa ni :—

**3d. 6d. 9d. 1s.**

A nsi ilẹkun di agogo kan ọsọsan Thursday.

A si nti ilẹkun ni agogo meje alalẹ Satide.

Editor :—
ADEOYE DENIGA,
Offices: 22 & 24, Williams Street,
P.O. Box 286,
Lagos, Nigeria.

ASAN-SILẸ NI OWO GBIGBA RẸ.

| Eko. | | Ilu miran ni Nigeria. | Ilu Okere. |
|---|---|---|---|
| Ọdun kan | 12/- | 13/- | 14/- |
| Ọṣu mẹfa | 6/- | 6/6d. | 7/- |
| Ọṣu mẹta | 3/- | 3/6d. | 4/- |

Ẹ fi owo ati *Letter* ranṣẹ si *Editor*.

## GBOHUN-GBOHUN.

:o:

AIYE LA B'OWO!

A mu ọfọ Ọgbẹni J. F. Branco lati Ajaṣẹ wa fun awọn ọmọ ati ẹbi rẹ ni'le rẹ ni Kakawa *Street* ni'lẹ yi ni Satide to kọja. Nigbati ẹnikan sọ pe ile ti Ọgbẹni na ni ni'lẹ yi to adọta, ti pupọ ninu rẹ jẹ fi-ọngbọn fi-ọngbọn laika ọgọrọ ẹgbẹgbẹrun pọnun ti a gbọ pe o ni ni *bank* nibi, tabi awọn ile ti a gbọ pe o ni ni Ajaṣẹ ati Mahin ilu rẹ, a mi ori wa, a si lọgun pe "Nitotọ awa ko mu ohun kan wa si aiye yi, o si da ni loju pe a ki yio mu ohun kan lọ" gbogbo rẹ iyẹpẹ ni.

A ba awọn ẹbi ologbe na kẹdun ọfọ yi.

Ẹ PẸLẸ ỌJỌ.

Ni *Tuesday* ọsẹ to kọja ni ihin kikun omi kan ni Ibadan kan ni. Ẹnikan to ri omi na sọ pe o mu enia tan patapata; pupọ ile lo si wo; a gbọ pe o gbe ile Ọgbẹni T. Hannibah Johnson lọ ati ile Ọgbẹni Ali Johnson; bẹ si ni a sọ pe o ru *African Church* ti o wà leti ibẹ na lọ patapata; a ki awọn ara wa, ẹ pẹlẹ ọjọ, a si ki awọn to ku ẹ ku ewu.

INA !!! INA !!! INA !!!

Ẹ B'OMI SI I, Ẹ B'OMI SI I.

Orin awọn ọmọ-ile-iwe yi lo ba ina kekere kan to jo ni arọ kùtùkùtù *Tuesday* ọsẹ yi ninu ile kan ti o jẹ ti Alufa Salami Ogunro ni 27, Isalẹgangan *Street* mu; a gbọ pe ko si ẹniti o mọ bi ina na ti ṣẹ, ṣugbọn ka to ṣẹju pẹ, o ti di pipa.

ṢE IWỌ MỌ, O ṢE ṢE E.

Ara ta Oyinbo Ijọra kan ni Satide ọsẹ to kọja, nigbati on ati Oyinbo ẹgbẹ rẹ njijọ nta tẹtẹ pọ, tobẹ ti a gbọ pe "Gbau" ibọn lo ni ki ekeji on wa gba ni igba aiya nigbati ara rẹ kọ fun jijẹ ti a gbọ pe ekeji rẹ na jẹ; ṣugbọn ori yọ Oyinbo keji yi, nitoripe ibọn na tàsé rẹ, a si sọ pe ãrà rã a mọlẹ tobẹ to fi jẹ pe nibiti o ṣe wọ si fun ẹrù, nibẹ lo sùn titi ilẹ ijọ keji fi mọ bã; Hã hã hã ni awọn ọmọ ọdọ rẹ ṣe nigbati nwọn ri ọga wọn to fẹrẹ di ẹran ogun nijọna. A tanma pe awọn olori ọlọpa yio wadi ọran yi finifini, ki a to le fi abọ ọrọ na han ẹnyin ilu.

SA ASALA FUN ẸMI RẸ,

EKUTE D'ORO, O GBO'DE LỌNA ẸHINGBẸTI.

Awọn bi ọdunrun enia (300) ni a gbọ pe Ijọba ko lọ si Abẹkun lọsẹ tokọja nitori rogbodiyan Ajinipa Arun ode isinsinyi; Ijọba si ti pà laṣẹ fun gbogbo awọn to ngbe Alakoro, Idunmọta titi o fi de apa Ebute Ero ki olukuluku ma jafara lati ko kuro ni awọn adugbo wọnyi, nitoripe Arun na ti ran de awọn agbegbe ibẹ.

ỌBA LO T'EHIN ERIN FỌN.

Akanṣe Iwe-irohin Ijọba (*Nigeria Gazette, Extraordinary*) to jade ni *Monday* ọsẹ yi, sọ ti ilẹ tamutamu ti Ijọba npete lati gba ni ọna Yaba lọ si Atan; a si wi fun ẹnikẹni to ba ni ilẹ nibẹ, ki nwọn ma jafara iwe kikọ si wọn pẹlu iye ti olukuluku nfẹ fun ilẹ tirẹ to wa ninu eyiti Ijọba nfẹ gba na titi ọsẹ mẹta loni; a woye pe ile ni nwọn ma fi kọ fun awọn

enia ti a o şi kuro ni ibiti o ba fun ju ni'lẹ yi, bi Alakoro ati Oko-Awo.

A gbọ pe yio to ẹdẹgbẹrin *Acre* ti Ijọba nfẹ ninu ilẹ na (*700 Acres*) ati pe owo ti Ijọba yio mu ninu owo ilu şe inawo nkan wọnyi le to nkan bi (*£220,000*) ọkẹ mọkanla pọnun ninu eyi boya iye ti nwọn yio yọda ni sisan fun gbogbo awọn oni'le yio jẹ (*£50,000*) a si tun gbọ pe o le to ẹgbẹrun Ahere (*1000 huts*) ti a o kọ sibẹ, yio si ni oju ọna (*Roads*) nlanla, pẹlu ina, omi ati orişirişi nkan lilo miran; gbogbo inawo eyi le to nkan bi (*£170,000*.)

Bayi ni a şi gbọ agbọsọ na si. Ipade Igbimọ Aşofin ti Ijọba mbẹ ni ọjọ *16* oşu to mbọ lati fi aşẹ si gbogbo ètò yi.

ARA ỌRUN KẸKẸ KẸ, E KU'RIN.

O to ọgọrun ẽgun to jade ni *Tuesday* ọsẹ yi nipa ètùtù ti a nşe ni'lu nisisiyi; nwọn si de Oju Ọlọbun lati şe bi o ti jẹ nibẹ pẹlu.

ABỌ O, ỌMỌ GBADEŞIRE.

A ba Ọgbẹni S. A. Johnson, ọkan ninu awọn Akọwe pataki ti *P.W.D.* nibi yọ fun ọmọkọrin kan ti Iyawo rẹ fi ta a lọrẹ ni *Friday* ọsẹ to kọja ni 28 Agbo-malu *Court*.

OLOGBE ỌGBẸNI J. O. BECKLEY ỌRUN RE.

A o şe isin iranti Ologbe Ọgbẹni J. O. Beckley ni Ile-isin *Ebenezer* ni Agege l'ọla ni agbara Baba ni agogo mẹta ọsan.

A bẹ gbogbo ẹnyin ẹjulumọ, Ibatan, Ara ati ọrẹ lati wa sibi isin na.

ADIẸ ŞOKUN IYẸ, IYẸ DI YẸGBẸYẸGBẸ.

Lati igbati Ajakalẹ Arun ode isinsinyi ti bẹ silẹ, ni ilu ti nsọkun õgun ti a le fi le lọ: awọn Ijọba ko si sinmi, nwọn ko si baye lati rẹ wa lẹkun: ni lọlọyi, Ijọba ri ọgọrọ Õgun ti a npe ni *Anti-plague Vaccine* gba lati Ilu Oyinbo ti o le le arun na lọ bam-bam: o si ti di lilo fun gbogbo enia nipa pe ki a tọ awọn Dokita ilu lọ fun Igunpa lati fi Egbogi na si: inu wa si dun gidigidi nigbati a ri awọn şaşa-werẹ wa ati awọn agbalagba ti nwọn nwọ to awọn Dokita lọ fun Egbogi na: şugbọn anu şe ni lati ri pe a tun nri ọpọlọpọ awọn ẹlomiran ti nwọn nkan'di m'ẹhin fun egbogi na: eyi ko tọ rara: awa papa la nşaroye pe a fẹ õgun ti yio ki arun yi wọ, awọn Ijọba si tun fi egbogi na fun wa lọfẹ—nipa lilọ gunpa lọdọ awọn Dokita fun fifi ogun na si, a si tun nsa sẹhin, itumọ eyi o? Nitorina, ẹniti ko ba ti lọ gunpa tirẹ ki o ma şa lai lọ fun ilera ara rẹ. E ma jẹ ki edi Arun na mu nyin o.

---

Badagry.

Sept. 11, 1924.

Si On-iwe Irohin "*Eko Akete*"

Gafara o,

Ohun pataki kan nbẹ ti a ko ni anfani rẹ. Bẹni ko si ọna ti a le gba fi ri anfani nkan yi ju "*Eko Akete*" lọ, ohun na ni pe lọsọsẹ ni a ma nka iwe irohin rẹ "*Eko Akete*" ni aka gbadun, ti o si jẹ wipe a ko m'ala kọbọ mẹrin ti a fi nra mọ.

Şugbọn a ko nri ka ninu rẹ, nipa Ọkọ Ẹlẹfin ti yio lọ ati eyiti yio bọ lati ilu Oyinbo, ọjọ ti wọn yio ma gbera kuro ni Eko ati ọjọ ti omiran yio wọle. Eyi ni ohun pataki ti o nşe ọrandun mi nitorina mo fẹ ki aye kekere kan niba jaba ki o wa ninu iwe irohin yi ki a ba le ni anfani ribiribi yi. Bi "*Eko Akete*" ba le ma şọ fun wa gẹgẹ bi mo ti wi yi ng o mọ pe dajudaju "Iwọ" ni alagbawi awọn odi.

Mo dupẹ aye ti o fun mi yi.

*Eko Akete* ọwọ rẹ a roke dandan o ko ni ifi ọpa tẹlẹ ni bu jẹbọ ki o to r'aje jẹun.

Wa pẹ ki o to ku, o ko ni pẹ ki o to la, aiye rẹ a dara, temi a toro dandan.

Emi tirẹ nitotọ,

ALAWIYE.

## *Open Letters.*

TO CELEBRITIES, NOTORIETIES, ETC., IN DIFFERENT WALKS OF LIFE.

**No. 49.**

To

THE VENERABLE T. A. J. OGUNBIYI L.TH.
*Archdeacon of Lagos,*
St. Paul's (Breadfruit) Church,
Lagos.

Misguided Archdeacon,

Why you, a high-placed ecclesiastic, should have given occasion for our veteran contemporary, The *Lagos Weekly Record*, to set the Thames on fire by the publication of the damning, yet true state of affairs relative to the settlement of your Libel Action against the redoubtable Editor of that journal in its last issue, beats my time.

After your *tacit consent* to have the palaver settled "out of Court" when those three gentlemen—peacemakers I call them—came to you on Sunday the 31st *ultimo* with reference to the matter, as reported in the *Weekly Record* under review, what, in the name of reason, is the necessity for your Yoruba Sermon partly on the same subject to have found its way to the reading world in the columns of The *Nigerian Spectator* of the 13th instant—barely *two weeks after the Peace Mission* to you? Do you want me, or the general public for that matter, to form the impression of your not being true to yourself, of blowing hot and cold at the same time, or of cutting your nose to spite your face? Now that the die has been cast, that what has been allowed to hide, is preached in the house-tops, may I ask you, in all seriousness, in what position you place those Godly men, to wit, Messrs Peter J. C. Thomas, J. A. Odufunlade, J. T. Nelson Cole, and E. J. Alex Taylor, men who have no axe to grind in the matter, but who on the contrary, have been unsparing in their efforts since Mr. Thomas H. Jackson the Editor of our Contemporary has yielded to the settlement of the unsavoury business "to save the Race and protect the Church"?

Is this thy gratitude to thy 'saviours'? Would the public be justified in applying this saying to your inglorious conduct in this regrettable drama, *Quem vult perdere, Jupiter prius dementat*, (those whom the gods wish to destroy are first deprived of their senses.) By the publication of the "Real Truth" in the columns of our contemporary under reference, to which publication, I am strongly convinced you are a party, through breach of confidence as has been abundantly proved by that paper, think of the embarrassment to which the peacemakers have been subjected, think, of the filth gathering about your name, to say nothing of your high Office as Archdeacon of Lagos,! Shades of NICOLSON, of JOHNSONS, of WILLOUGHBY, defend us !!!.

But of one thing you may be sure, and that is, by their unsolicited intervention, these peacemakers have observed,

"The Oath of Allegiance they owe to their country and Race,

And the Discharge of same faithfully."

After all, man's greatest enemy is HIMSELF.

EKO AKETE.

Si Oniwe-irohin *Eko Akete*

Mo juba o:

Gbogbo wa lo mọ pe "Owe ni ẹṣin ọrọ bi ọrọ ba sọnu owe la'fi nwa" "Alemu o ya'gba K'agba ma ṣe'hun alemu" *Ohun ti o ba jọra wọn lafi nwe ara wọn.*

Ni ọdun diẹ sẹhin ariwo sọ jakejado gbogbo Eko a ti ilu agbegbe to wa yika pe ọkunrin babalawo kan nbọ wa si Eko ati pe iṣẹ awo rẹ daju, ẹjẹ ni babalawo yi si nmu.

Lẹhin bi ijọ mẹta ti okiki yi ti nkan babalawo yi wọ ilu pẹlu ero pupọ, gbogbo ilu dide lo pade rẹ nitori orukọ rẹ ti a ti ngbọ, aṣe IMANU ni babalawo yi njẹ; gbogbo ilu nwọ lọ pẹlu ẹbọ oniruru on papa si nṣe bi arira. Awọn agbalagba lo npa lowe pe, bi aiye ba nyẹni iwa ibajẹ la nhu" IMANU tilẹ fẹrẹ sọ ara rẹ di MALAIKA ṣugbọn gẹgẹ bi oriki Baba-Yeye "Girigiri lẹhin aṣododo a kọ ma ti ika lẹhin."

IMANU gbagbe ara rẹ pe alejo ni on ni ilu Eko, o si ngbidanwo lati de ade o si nfẹ fẹ ọmọ ọba ilu ni aya. Ni akoko ti babalawo yi koi fi ti obinrin sinu iṣẹ awo, rẹ gbogbo ilu t'ọkunrin t'obinrin lo nlọ wa'ri fun ṣugbọn nigbati on wa nrope on gbọn pupọ ti o si ntẹ gbogbo obinrin Eko ni bafin awọn ilu dorikodo nwọn si ṣe ohun ti o tọ fun. Agbaregbabọ, "atẹ ilẹkẹ si di atẹ ọrunla" eyin jẹran-jẹran di eyin fọgunfọgun eyi fihan wa daju pe ni atetekọṣe obinrin lo ṣe iṣubu baba nla wa Adam.

Ara ilu, bi a ti nsọ lọwọ yi, a le ri iru ẹṣẹ IMANU babalawo yi larin wa lode isinsin.

Babalawo miran kan dide lakoko kan lati lo kọ iṣẹ awo rẹ dajudaju lokere ati lọdọ awọn ti o gboju, inu t'ọmọde t'agba ilu dun lati ri alakikanju alawo bẹ.

Nigbati o wa awo yi de ilu okere babalawo yi bẹrẹ si ranṣẹ firifiri si'le. Ki a ma da lọ popopo babalawo yi pada wa ile lati irin ajo rẹ, gbogbo ilu, lo tilẹ lọ yọ fun ti nwọn si ki kabọ. Lẹhin oṣu diẹ sẹhin ogbologbo awo bẹrẹ si fi ohun titun han, eyini ni pe o sọ ara rẹ di ayọrunbo nipa bayi gbogbo awọn obinrin ti ko ri ọmọ bi nlọ ṣe awo lọdọ rẹ ki nwọn ba le ri ọmọ bi; irohin na tan ka'lẹ tobẹ ti awọn obinrin miran ko tilẹ tun u ngbọ ọrọ si ọkọ wọn lẹnu nipa ọgbọn ete ti Ọdẹlẹsinrin yi fi nṣe awo okunkun fun awọn obinrin; iwa buburu yi ndagba si ninu okumarata babalawo yi tobẹ ti o fi gbagbe pe ẹda lasanlasan ni on. Eti nta gbogbo ilu fun iwa ibajẹ wonyi ṣugbọn nigbati akoko ti Oluwa koi to, ara'le mi ṣe bi ọgbọn on ni, Loni nkọ? Ẹnikẹni mọ iru ẹṣẹ ti oluwarẹ yi fi nṣe ayọ, ara ilu ẹ ko ri pe ohun to ba jọra wọn la fi nwe ara wọn, tani ko mọ babalawo

# Open Letters.

TO CELEBRITIES, NOTORITIES, ETC., IN DIFFERENT WALKS OF LIFE.

**No. 49.**

To

THE VENERABLE T. A. J. OGUNBIYI L.TH.
*Archdeacon of Lagos*,
St. Paul's (Breadfruit) Church,
Lagos.

Misguided Archdeacon,

Why you, a high-placed ecclesiastic, should have given occasion for our veteran contemporary, The *Lagos Weekly Record*, to set the Thames on fire by the publication of the damning, yet true state of affairs relative to the settlement of your Libel Action against the redoubtable Editor of that journal in its last issue, beats my time.

After your *tacit consent* to have the palaver settled "out of Court" when those three gentlemen—peacemakers I call them—came to you on Sunday the 31st *ultimo* with reference to the matter, as reported in the *Weekly Record* under review, what, in the name of reason, is the necessity for your Yoruba Sermon partly on the same subject to have found its way to the reading world in the columns of The *Nigerian Spectator* of the 13th instant—barely *two weeks after the Peace Mission* to you? Do you want me, or the general public for that matter, to form the impression of your not being true to yourself, of blowing hot and cold at the same time, or of cutting your nose to spite your face? Now that the die has been cast, that what has been allowed to hide, is preached in the house-tops, may I ask you, in all seriousness, in what position you place those Godly men, to wit, Messrs Peter J. C. Thomas, J. A. Odufunlade, J. T. Nelson Cole, and E. J. Alex Taylor, men who have no axe to grind in the matter, but who on the contrary, have been unsparing in their efforts since Mr. Thomas H. Jackson the Editor of our Contemporary has yielded to the settlement of the unsavoury business "to save the Race and protect the Church"?

Is this thy gratitude to thy 'saviours'? Would the public be justified in applying this saying to your inglorious conduct in this regrettable drama, *Quem vult perdere, Jupiter prius dementat*, (those whom the gods wish to destroy are first deprived of their senses.) By the publication of the "Real Truth" in the columns of our contemporary under reference, to which publication, I am strongly convinced you are a party, through breach of confidence as has been abundantly proved by that paper, think of the embarrassment to which the peacemakers have been subjected, think, of the filth gathering about your name, to say nothing of your high Office as Archdeacon of Lagos,! Shades of NICOLSON, of JOHNSONS, of WILLOUGHBY, defend us !!!.

But of one thing you may be sure, and that is, by their unsolicited intervention, these peacemakers have observed,

"The Oath of Allegiance they owe to their country and Race,
And the Discharge of same faithfully."

After all, man's greatest enemy is **HIMSELF**.

EKO AKETE.

---

Si Oniwe-irohin *Eko Akete*
Mo juba o:

Gbogbo wa lo mọ pe "Owe ni ẹṣin ọrọ bi ọrọ ba sọnu owe la'fi nwa" "Alemu o ya'gba K'agba ma ṣe'hun alemu" *Ohun ti o ba jọra wọn lafi nwe ara wọn.*

Ni ọdun diẹ sẹhin ariwo sọ jakejado gbogbo Eko a ti ilu agbegbe to wa yika pe ọkunrin babalawo kan nbọ wa si Eko ati pe iṣẹ awo rẹ daju, ẹjẹ ni babalawo yi si nmu.

Lẹhin bi ijọ mẹta ti okiki yi ti nkan babalawo yi wọ ilu pẹlu ero pupọ, gbogbo ilu dide lo pade rẹ nitori orukọ rẹ ti a ti ngbọ, aṣe IMANU ni babalawo yi njẹ; gbogbo ilu nwọ lọ pẹlu ẹbọ oniruru on papa si nṣe bi arira. Awọn agbalagba lo npa lowe pe, bi aiye ba nyẹni iwa ibajẹ la nhu" IMANU tilẹ fẹrẹ sọ ara rẹ di MALAIKA ṣugbọn gẹgẹ bi oriki Baba-Yeye "Girigiri lẹhin aṣodẹdo a kọ ma ti ika lẹhin."

IMANU gbagbe ara rẹ pe alejo ni on ni ilu Eko, o si ngbidanwo lati de ade o si nfẹ fẹ ọmọ ọba ilu ni aya. Ni akoko ti babalawo yi koi fi ti obinrin sinu iṣẹ awo, rẹ gbogbo ilu t'ọkunrin t'obinrin lo nlọ wa'ri fun ṣugbọn nigbati on wa nrope on gbọn pupọ ti o si ntẹ gbogbo obinrin Eko ni bafin awọn ilu dorikodo nwọn si ṣe ohun ti o tọ fun. Agbaregbabọ, "atẹ ilẹkẹ si di atẹ ọrunla" eyin jẹran-jẹran di eyin fọgunfọgun eyi fihan wa daju pe ni atetekọṣe obinrin lo ṣe iṣubu baba nla wa Adam.

Ara ilu, bi a ti nsọ lọwọ yi, a le ri iru ẹṣẹ IMANU babalawo yi larin wa lode isinsin.

Babalawo miran kan dide lakoko kan lati lo kọ iṣẹ awo rẹ dajudaju lokere ati lọdọ awọn ti o gboju, inu t'ọmọde t'agba ilu dun lati ri alakikanju alawo bẹ.

Nigbati o wa awo yi de ilu okere babalawo yi bẹrẹ si ranṣẹ firifiri si'le. Ki a ma da lọ popopo babalawo yi pada wa ile lati irin ajo rẹ, gbogbo ilu, lo tilẹ lọ yọ fun ti nwọn si ki kabọ. Lẹhin oṣu diẹ sẹhin ogbologbo awo bẹrẹ si fi ohun titun han, eyini ni pe o sọ ara rẹ di ayọrunbọ nipa bayi gbogbo awọn obinrin ti ko ri ọmọ bi nlọ ṣe awo lọdọ rẹ ki nwọn ba le ri ọmọ bi; irohin na tan ka'lẹ tobẹ ti awọn obinrin miran ko tilẹ tun u ngbọ ọrọ si ọko wọn lẹnu nipa ọgbọn ete ti Ọdẹlẹsinrin yi fi nṣe awo okunkun fun awọn obinrin; iwa buburu yi ndagba si ninu okumarata babalawo yi tobẹ ti o fi gbagbe pe ẹda lasanlasan ni on. Eti nta gbogbo ilu fun iwa ibajẹ wọnyi ṣugbọn nigbati akoko ti Oluwa koi to ara'le mi ṣe bi ọgbọn on ni, Loni nkọ? Ẹnikẹni mọ iru ẹṣẹ ti oluwarẹ yi fi nṣe ayọ, ara ilu ẹ ko ri pe ohun to ba jọra wọn la fi nwe ara wọn, tani ko mọ babalawo

yi, eyiti iba ma fi ṣe iṣẹ awo rẹ lọna ti o tọ nṣe ni alaṣejuyi nda gba si ninu ẹṣẹ njẹ iwọ alawo ti o ngbabọdi, iwọ alawo ti o nṣe aṣemaṣe, gbogbo, iwọ alawo ti o fi ọrọ awo silẹ bikoṣe Bisibẹke, iwọ alawo ti o fi iṣẹ rẹ silẹ ti o nṣe ayọnusọ si ọrọ miran, mo dajudaju pe ẹsan mbọ. Ṣiọ! iwọ lana, iwọ loni, bi ẹkun apọkọ jẹ. Ngo tun fi aṣiri kan han fun nyin ni ọsẹ to'mbọ. Ki Baba ma ṣai ba wa ti babalawo yi siwaju.

Mo dupẹ lọwọ rẹ oniwe-irohin *Eko Akete* fun aye diẹ ti o fun mi.

Emi ni ti nyin nitotọ,
AKIRIMANU.

---

# *EKO AKETE.*

EKO, SATURDAY, SEPT. 27, 1924.

---

## A TA'GO K'ẸYIN APARO, OHUN OJU WA L'OJU NRI.

Gudugbẹ̀ to ja nigbati Iwe-irohin *Lagos Weekly Record* jade ni *Sunday* to kọja mu ẹnikẹni bere pe "enia le fi ọwọ ara rẹ ṣe'ra rẹ bayi?" "A nj'ekuru ko tan, a si tun ngbọn'wọ rẹ s'awo" eyi si mu wa ranti orin yi :—

Okete bayi ni' wa rẹ
O ba' Fa mu'lẹ
O da' Fa.

Kò dede ti a fi gb'ẹnu le ọrọ a ba ni l'orukọ jẹ, a ko ba ni l'orukọ jẹ, ti *Archdeacon* T. A. J. Ogunbiyi sọ di ẹjọ "Ganran" pẹlu Ọgbẹni Thomas H. Jackson Oni'we-irohin *The Lagos Weekly Record*, nitori ko si bi ariwo ẹjọ na ko ti mi ilẹ yi to lati iwọn oṣu meji to kọja.

Nigbati awọn alagba bi—Ọgbẹni Peter J. C. Thomas, J. A. Odufunade, J. T. Nelson Cole ati E. J. Alex-Taylor—awọn ẹniti Ọlọrun mã kẹ bi o ti kẹ Morẹnikẹ ni'le Ilọrin—dide lati tẹ gãsi ọrọ na ba'wọ ki nwọn si pari rẹ ni itunbi-inubi ti Egun npe ni iyekan, ko si ẹniti ko dun mọ ninu, pãpã fun irufẹ-ifẹ-nini si ara ẹni ti a ti ngbadura rẹ lọjọ to pẹ pe ki o maṣai mã pọ si larin awa ọmọ *Africa* nibi.

Tõtọtõtọ awọn bọkinni yi si mu ọna iṣẹ-ifẹ wọn pọn lẹhin igbati Ọgbẹni Jackson ti gb'ojẹgẹ fun wọn lati pari ọrọ na ni'le, ti o si sọ oriṣiriṣi ohun ti on nfẹ (ki iṣe owo tabi ẹbun kan rara o,) gẹgẹ bi a o ti la fun ẹnyin ọkawe wa ninu iwe yi. Nwọn lọ si ọdọ ọlọrọ̀ pãpã eyini ni *Archdeacon* Ogunbiyi ni *Sunday* ọjọ *31* oṣu to kọja, o si yọ̀yọ̀ pe on nfẹ ki ọrọ na pari ni'le ati pe on ko tẹ ṣe ogun Kotu mọ; nwọn si sọ fun pe ki o maṣe gb'ẹnu le ọrọ na rara ibaṣe lori Aga Iwasu rẹ ni, tabi lọna miran; nwọn si ni awọn pãpã yio sapa ki Iwe-irohin kọkan ni'lẹ yi maṣe sọ si i rara. Gbogbo eyi ni awọn Ọgbẹni ẹni Ọlọrun wọnyi ṣe, ti nwọn nti ile de'le, o si dani loju pe *Archdeacon* pãpã jẹ ọhẹn si gbogbo ohun ti a ba sọ na gẹgẹ bi o ti wa ninu Iwe-irohin *Weekly Record* ti ọsẹ to kọja.

Ṣugbọn iná tun ru nipa Iwasu Yoruba ti *Archdeacon* na wà nipa ọrọ yi ni ọjọ *6* oṣu *July* to kọja; ni Ṣọṣi rẹ (*Breadfruit*) ti a si tẹ sinu Iwe-irohin *Nigerian Spectator* ti ọjọ *13* oṣu yi.

Mọṣãṣi ọrọ ti Iwe-irohin na si sọ nipa ẹjọ yi, fọ gbogbo nkan loju pọ.

Dajudaju bi *Archdeacon* Ogunbiyi ko ba fi Iwasu na ṣọwọ si Oniwe-irohin *Nigerian Spectator*, ki o si sọ fun u pe ki o tẹ ẹ sinu Iwe-irohin rẹ, bawo ni onitọhun ṣe ma gbojugb'aiya hu iwa alaironu bẹ, nipa titẹ Iwasu oni'wasu sinu Iwe-rohin rẹ lai gba'ṣẹ?

Ṣugbọn iwa *Archdeacon* yi dabi :—

Ẹlulu to fa'jo,
Ori ara rẹ lo fã le.

A ngbèjà Ọ̀jà, Ọjà ni ta lo njà lẹkulé on; nisisiyi, nigbati Iwe-irohin *Record* ti a nsọrọ rẹ yi ti "tu ifun ọni" gbogbo ọrọ na, ti o si tun la ọrọ miran mọlẹ wà bi ẹni gbe ọ̀pẹ̀lẹ̀ ṣanlẹ̀, nipasẹ ti ọdọmọbinrin kan ni Ode Ondo, ti orukọ rẹ njẹ Alice Ademọ̀jàrẹ̀ ti *Archdeacon* yi ba l'ori jẹ, nigbati o ṣi wa ni Alufa lasan labẹ Ṣọṣi *C.M.S.* ni ilu na, gẹgẹ bi *Record* ti ọsẹ to kọja ti sọ fun ni.

Ki a sọ pe odidi oloye *Archdeacon* Ogunbiyi tun le wa nipo sisọ ọpa oke s'ọpa odo, pe o tun le wa nipo ọ̀dàlẹ̀— nipa pe o ba awọn sanmari Apari-ija na fi Okete san ọgọfà, nigbati o si tun gba ọna ẹbùrú lọ fi okõ kun u, ṣe nse lo fi ẹhin awọn enia rere yi da õgun niyẹn nipa titẹ Iwasu na gẹgẹbi a ti sọ niṣiwaju.

Ki lo tilẹ nya apari l'ori ti o nmokun lodo? Búni-búni ab'ẽbú wọ̀-ntiti-wọ̀-ntiti; á ngba ðromọ́ adiẹ lọwọ iku, o ni nwọn ko jẹ ki on lọ si atan lọ jẹ.

Njẹ oju ko ha ti *Archdeacon* na pe iwa yi rẹ on silẹ patapata bi A ko Ijọ Kristi jẹ?

*Archdeacon* Ogunbiyi fun ara rẹ lo tẹ ọka n'iru, ti o fi ri ija ejo. On papa lo pa Inaki, o si yẹ ki o gbe Inaki rẹ̀ pọn.

Ilu ṣọpẹ gidigidi lọwọ awọn Ọgbẹni Peter J. C. Thomas, J. A. Odufunade, J. T. Nelson Cole ati E. J. Alex Taylor fun ãjo ati ãyan wọn lati tẹ oju ọrọ na bọ'mi nitori rere Enia Dudu ati nitori idabobo Ijọ Enia Olorun. (*To save the Race and protect the Church*) ṣugbọn Aja to ma sọnu ki gbọ ðfé.

Bawo ni o ti gbadun orin yi si ẹnikeji? Sa kọ na.

> "*Spectator* pa ọrẹ rẹ̀
> Gbe e, gbe e, o bẹrẹ gbẽ
> Kilo ba wa o,
> Ẹnu aiṣọkan ni."

---

## ÀGBAKÒ, ORI EDE.

[ *Wosika lati ọwọ* ATARI-AJANAKU. ]

Si Oni'we-irohin "EKO AKETE."

Mo bẹrẹ f'oji,

Adura ti gbogbo ẹda ngba l'aiye lojojumọ ni pe ki Ọlọrun maṣe jẹ ki a pade agbako. Eyi fihan ni pe Anjọnu buburu ni Agbako, kosi si oloraye to r'aye ju agbako lọ; iru ni, ki ng nwọn l'ọbẹ.

Agbako a ma yọ si enia lojiji nigbamiran; nigba pupọ, ẹwẹ, ẹlomiran nfi iwa ati iṣesi rẹ p'olowo bi ẹni p'olowo ọja kakiri ilu pe "Ẹniti o ni agbako ki o ta fun on."

Ole, ọmutipara, panṣaga, agbèrè, abinuẹni, ofofo ati awọn oni janduku iwa miran gbogbo lo gbe ọpa wahala dani fun'ra wọn, ti nwọn si nwa agbako kiri lojojumọ. Bi iru awọn ẹni bẹ ba pade agbako nibiti agbako lugọ si bi ọdẹ, ohun ti oju wa, ni oju ri. Sibẹsibẹ, eniti omí ba pọ loju rẹ le sọkun fun wọn.

Njẹ ti a ba ri enia to le sọkun nitori idãmu ti o ba ẹniti o fi ọwọ ara rẹ wa agbako kiri bayi, ti o si ri i, melomelo ni a o ri ọpọ enia ti yio ba ẹniti agbako tọ wa si'le rẹ kẹdun idamu, wahala ati iyọnu rẹ.

### AGBAKO, OKO AWO.

Jẹjẹ ni ile won ni awọn ara Oko Awo joko ki agbako to wọ ile tọ wọn, to si bẹrẹ si fi nwọn le iku lọwọ. Kẹrẹkẹrẹ, a tun ngburo Anjọnu apanirun yi kiri adugbo miran. Ẹlomiran kuro ni Oko Awo nitorina, o sa lọ si Idumata, laimọ pe agbako ti lugọ de on nibẹ.

Nigbati o ṣe, awọn Dokita olutọju ilu bẹrẹ si fẹ oju mọ agbako yi, ki o le pada lọ si orile rẹ, anu si ṣe ni pe titi di oni, o dabi ẹnipe agbako yi nfi oju tinrin wọn.

Bi arunkarun ba wọ ilu kan, ipa ni a fi le le e jade kuro nibẹ, lati igbati Ijọpa si ti wipe *Bubonic Plague* pa ẹnikan ni oṣu keji ọhun, *July* 28, ni nwọn ti bẹrẹ aisimi, aibaye, lati ge arun yi ni igberi, ki o maṣe le gb'ilẹ larin wa.

A dupẹ pupọ fun ãjo nla ti Ijọba nṣe bayi, ipo wa si ni lati ran nwọn lọwọ de opin agbara wa. Ṣugbọn ajo wo ni nwọn nṣe, ati irufẹ iranlọwọ wo ni a le ṣe fun wọn? .

### AJO IJỌBA.

Afọju papa nri iran ri *Kerosine* epo Oyinbo ati ohun olorun miran ti nwọn nfun si enia lara lọna Oyigbo; aditi ngbọ pe nwọn nko enia lọ si Ikoyi, oju awọn Dokita papa ni nwọn si ṣe nta abuku fun wọn, nipa gbigba oku alaisan ti nwọn tọju lọ la ni ile oku, lai ka iwe ẹri tabi *Death Certificate* wọn si.

Gbogbo nkan wọnyi ni Ijọba nṣe ati jubẹ lọ, iranlọwọ ti nwọn si nfẹ lọdọ wa, lẹhin itọju ara ati imọtoto, ni lati di iho ekute, lati ma ṣe ofofo ẹnikẹni to ba ṣaisan ojiji, lati ma tu ọfọ oku oloku ati lati ma yọda ara wa fun kiko lọ si Ikoyi nigbakigba to ba wu Ijọba lati ti ilẹkun ile wa.

Ẹnikẹni ti o ba ro pe Ijọba lè lé arun kuro ni ilukilu laisi inira diẹ, tabi inira rara, fun ara ilu na, oluwarẹ ntan ara rẹ jẹ ni; sibẹsibẹ, eyi ko wipe ki a maṣe wi'jọ ti a ba ri inira ti a ro pe ko tọ, inira ti a ro pe ko wọ, ati inira to le mu ifoya dani. Ti a ba dakẹ, ti ara wa yio ba wa dakẹ.

Nitorina, a o sọ nipa ire ati ibi ti a ro pe o wa ninu ajo ti Ijọba nṣe nisisiyi.

Ajo ṣiṣe jẹ ohun to dara lọpọlọpọ; ṣugbọn ki ajo to le ṣe iṣẹ rere, ẹniti a nṣe ajo fun ni lati mọ

agbara ajo na, ki inu rẹ si dun si i, bi bẹkọ, pabo ni !

Epo Oyinbo ati ohun olôrun miran ti nwọn nfun si enia lara l'ọna Oyigbo, enia melo ni Ijọba sọ ire pato to le ṣe fun (ju pe lati dabobo ara Ebute Mẹta ki arun na maṣe le de ọdọ wọn) ṣugbọn bi ẹniti nwọn ba fùn hùnrẹn wọn na si lara lẹkan, tabi lẹmeji, tabi lẹmẹta bọ patapata lọwọ arun ode yi ni o, wọn ko sọ fun ni. Eyi ti a mọ ni pe, nwọn nfun si ẹlomiran l'ọwọ, ẹlomiran aṣọ, ẹlomiran ẹsẹ, ẹlomiran idodo, papa awọn obinrin nitori ki ohun olôrun na le ṣan lati idodo wọn lọ si *isalẹ labẹ aṣọ*.

Ẹlomiran, ẹwẹ, nfi *Naphtaline Ball* tabi oriṣi kanfọ kan ṣe "tikiti" tabi "*passport*" irekọja lai gba epo Oyinbo s'ara.

Ewo le'wo ? Enia le lo egbogi kan lai mọ agbara ti o ni can tabi oniruru iṣẹ ti o le ṣe, a fẹ lati mọ iṣẹ rere pataki wo ni epo Oyinbo ati ohun olorun miran le ṣe lara. Ti o ba ṣe pe kiki pe ko ni jẹ ki arun kọja si ibomiran nikan ni, kilo ṣe ti won ko tete lo o fun awọn ara Oko Awo, ki nwọn maṣe le ko oriburuku won de adugbo miran ?

Ti o ba si ṣe pe, epo oyinbo ati nkan miran na ti nwọn nfun si enia lara lọna Oyibo ni agbara ati gba enia lọwọ arun ode yi patapata ni, kiloṣe ni ile ti ofo ṣe, ti a ko kuku nwipe ki nwọn ma fi epo Oyinbo pẹlu ọṣẹ para, dipo kiko ti nwọn nko wọn lọ si Ikoyi pẹlu gbogbo aladugbo ?

A mọ Dokita diẹ ti ko ka hunrẹn ti nwọn npe ni "omi ẹro" ti nwọn nfun si enia lara lọna Oyigbo si tobẹ, tabi de ipo ti nwọn fi le ni ki awọn Alufa Ṣọṣi bi Evan Williams, Solomon Pearce, etc., ati ọlọla obinrin bi Mrs Bagan-Benjamin etc., maṣe kọja lọ si Ebute Mẹta ni ọjọ ọsẹ kan, laiṣe pe a fi epo Oyinbo rẹ wọn l'aṣọ Ani, bi omi ẹrọ yi ba da Dokita olutọju ilu loju daradara, kiloṣe ti nwọn nfun si Enia Dudu lara, ti nwọn nfi Funfun silẹ, ti nwọn nfun si awọn obinrin Musulumi lara ju awọn Mammy oniyẹri lọ, ti nwọn nfun si Adelamu lara ju ọniọ Eko lọ ?

Njẹ ki a wipe ina tabi idun ara ekute to nmu arun yi wa ṣẹṣẹ de ara ẹnikan, ti koi da oluwarẹ na dubulẹ, a fẹ lati mọ ire wo ni epo Oyinbo ti nwọn ba fun si oluwarẹ l'ọwọ tabi l'ẹsẹ lẹhinna, le ṣe fun oluwarẹ ?

Gbogbo nkan wọnyi lo yẹ ki Ijọba sọ fun wa, ki nwọn tẹ ẹ sinu iwe fun wa ni ede Oyinbo, ati ti ilẹ wa ki nwọn lu agogo rẹ kiri ilu. A si tun fẹ lati mọ bawo ni ôrur. epo Oyinbo ti a fun si ni lara lẹkan ti le pẹ to lara, ki ipa rẹ to pin ?

A fẹ ki awọn Dokita wa ba Dokita Ọba jiroro lori ọrọ yi—nwọn sa jọ jumọ kọ iṣẹ pọ ni Ilu Oyinbo ni kẹ—ki nwọn ba wọn da ọrọ na ro, ni ireti a ti da "omi ẹrọ" duro, ti ko ba le ṣe iṣẹ rere kan pataki lara. Laisi ani-ani, ohun ikunsinu pupọ ni omi ẹrọ yi jẹ fun ero to nlọ, to nbọ ati ohun ẹru jẹjẹ fun ọpọlọpọ awọn ero idalẹ ibiti onjẹ ti nwa fun wa.

A ko le ma lo egbogi kanna titi lojojumọ bi aguntan ti ko pa aṣọ eṣi da, laimọ gbogbo iṣẹ rere ti o le ṣe. Ọpọlọpọ ninu awọn ti a ti fun epo Oyinbo si lara lẹmeji-meji lojọ wa ni Ikoyi nisisiyi, ninu wọn ti ku, tobẹ ti a fẹrẹ le bere wipe, kilopo ?

## IKONI LỌ SI IKOYI.

Nipa ti ikoni lọ si ikoyi ; Nitotọ, nigbati ajakalẹ arun ba wọ ilu kan o yẹ ki a ni ibikan bi *Isolation Hospital* ti a o ma ko ẹniti a ba mọ daju, tabi ti a ni ifura nla si pe o ni arun lara pamọ fun itọju. Ti a ba si ti yọwọ ile ti Ijọba yasi otọ fun awọn Aṣiwere ati Adẹtẹ ni Yaba kuro, ko si ile alarun pataki ti a le pe ni *Isolation Hospital* ni gbogbo ilu Nigeria jake, jado mọ.

Apakan ilẹ I k o y i ni I j ọ b a nlo gẹgẹ bi *Isolation Hospital* nisisiyi fun awọn ti Ijọba ro pe arun ekute tabi *Bubonic Plague* wa lara wọn. Ijọba kesi wa lati ṣe ofofo alaisan ojiji nitori ati le ko wọn lọ si Ikoyi pẹlu gbogbo ara ile wọn, ati ara ile awọn ti ọfọ ṣẹ pẹlu.

Ṣugbọn nigbati a ba nranti bi Ikoyi ti ri, ti a ba nranti ẹkọ ti nwọn njẹ nibẹ bi pakọkọ ti a ba nranti pe ko si Dọkita ti awọn alamodi ibẹ le kesi loru l'ojiji nitosi ọdọ wọn, ati pe bi Dokita tilẹ wa, wọn ko pọ to nibẹ, ti a ba nranti pe ṣaṣa enia lo le sun sori iru ibusun wọn nibẹ pẹlu irọrun, ti a ba ranti pe iye alamodi ti nwọn ni arun ekute ti pa nibẹ ju iye ti o da awọn Dokita loju lọ pe o ti pa ni arin ilu, ti a ba ranti pe aye to wa nibẹ fun alamodi totọtotọ lati dide lori akete rẹ, ko to eyiti alaisan le ri ni *Colonial Hospital* tabi labẹ itọju awọn Dokita wa, ti a ba ranti pe ẹniti o lọ si Ikoyi lẹkan, nwọn tun le mu u lọ sibẹ lẹkeji, ani ti a ba ranti otutu Ikoyi l'oru ati inira miran to wa nibẹ fun alaisan totototo, a ko sọ ti awọn ti a ko lọ gba afẹfẹ ijọ marun nibẹ, a ko le ṣai ṣe ẹnu tiko-tiko diẹ ki a to ṣe iṣẹ ọlọpa inu alaisan fun Ijọba.

O tilẹ yẹ ki Ijọba jẹki a mọ anfani to wa ninu ikoni lọ si Ikoyi, Abẹkun, Itirinrin tabi ibomiran fun ijọ marun tabi ju bẹ lọ, gẹgẹ bi iṣẹ wọn nisisiyi ; papa nigbati o jẹ pe alebu to wa lara ile alarun Ikoyi nisisiyi pọ ju on ti a le pe ni *The Proper Isolation Hospital* lọ.

A si fẹ lati mọ bi ina tabi idun ekute tun le jẹ ẹniti a ti ko lọ si Ikoyi lẹkan ri rara mọ, tabi o le jẹ ẹ ni ajẹpa lẹhin ti o ba ti jade nibẹ bi ẹniti ko tilẹ de Ikoyi ri, tabi bẹkọ. Ọpọlọpọ nkan nwọnyi ni Ijọba ni lati la ye enia, nipasẹ gbogbo ajo ati ohun ribiribi ti nwọn nṣe fun wa nitori amodi yi bi ede ko y'ede ba ti kuro nibẹ, iyoku fuyẹ.

Ṣugbọn titi a o fi la anfani rẹ ye ni yekeyeke, o yẹ ki Ijọba fi ẹlẹ ati ẹsọ si kiko ti nwọn nko enia kuro ni ile rẹ lọ si I k o y i

—nibiti ko daju pe o le ro oluwarẹ lorun bi ile, ti ko le ri iru gbogbo onjẹ ti o wu u, ati boya iru egbogi to ba a lara mu lati lo.

Gẹgẹ bi aboyun ni gbogbo ẹda ri, ati ọkọnrin ati obinrin. Onjẹ ẹnikan le jẹ majele ẹnikeji. Bi *Quinine* ti jẹ gbajumọ pataki ninu egbogi Oyinbo to yẹn, bi diẹ kiun ninu rẹ ṣeṣi kan ẹlomiran l' ẹnu, ọrun l' ẹrọ. Bi ẹlomiran njẹun lowọ, ti ẹnikan ṣeṣi tu itọ niwaju rẹ, yio bi (*Vomit*) gbogbo onjẹ ti o njẹ danu lẹsẹkanna Gari, ti a nkigbe rẹ yi, bi ẹlomiran fi kan ẹnu, o di ki o ma gbọnsẹ gburugbu; bi ẹlomiran ri ologbo lasan ni iyara, o di ki aisan ti a npe ni *Asthma* bẹrẹsi iyọ ọ lẹnu; gasi tabi ife ọti *Beer* kan le sọ ẹlomiran di ọbọ, bẹni ẹlomiran si le nikan da odidi igo O. T. G. s' ori ni 'joko ẹkan. Ijọ ti aboyun miran ba f' oju kan ẹjẹ, ijọ na ni oyun inu rẹ yio bajẹ, ibẹ ni aboyun miran npa adiẹ je fun 'ra rẹ ni Satide, Satide. Dokita to ba ri iṣẹ ṣe daradara yio jẹri si eyi pe, *igbagbogbo kọ ni egbogi kanna ndara fun aisan kanna.*

Ibaṣepe *Proper Isolation Hospital* wa pẹlu ọpọlọpọ Dokita nibẹ, ati onjẹ atata, ibusun daradara, *Library* iwe to pe ye, ati ohun itẹlọrun miran gbogbo fun alaisan, tani yio ha bẹru lati lọ si Ikoyi fun i t ọ j u to 'ba di "karangida? Laisi eyi, ifoya nla ni.

## REST HOUSE--GOVT. QUARTERS.

Nigbati a ba nri ile nla nla ti Ijọba nfi owo ilu kọ fun awọn oyibo onisẹ ọba kọkan kakiri ilu wa, iru ile ti boya pupọ ninu wọn ko ri gbe ni ilu wọn, ayaṣebi nwọn ba ẹlẹgbẹ wọn pin iyara kọkan gbe, bi awọn kurumọ ti nhaya ojule kọkan, tabi ki awọn Oyinbo haya *Hotel* gbe ni ilu wọn, a ko le ṣai ka a si obun itiju gidigidi fun Ijọba pe ko si *Isolation Hospital* pataki kan jake jado *Nigeria.*

## BERE BERE KO NṢI BERE. KI-TO-YI? AJASA O!

Gbogbo eyi ti a nsọ dun, a nkun sinu pe Ijọba nko enia lọ si Ikoyi, pe Ijọba nla oku, ṣugbọn kini ọlọla Lọya Kitoyi Ajasa ti wi ninu iwe irohin rẹ ti ọsẹ to kọja? O ni nigbati arun *Bubonic plague* yi de, ti ko si tete kuro ni ilu awọn *West Indian* kan, o ni ile ẹnikẹni ti nwọn ba ri arun na di fifi ina sun titi yio fi di eru, ati wipe nigbakigba ti Ijọba ilẹ yi ba ro pe o tọ loju awọn na lati ṣe bẹ ẹ gẹgẹ fun wa, ki nwọn maṣe jafara lati fi ina sun ile ẹnikẹni ti amodi ode yi ba wa lara rẹ, ki-Ijọba si fun onile lowo ofo rẹ. Njẹ, a tun bere, ki-to-yi-i? Ajasa O! Baba, maṣe jẹ ki a ri ogun ti Ijọba yio fi bẹrẹ si da ina sun ile wa nitori orun ekute.

## IBUPA ALABẸRẸ TABI *INOCULATION.*

Ọna ti Ijọba ngba nisisinyi lati le *Bubonic Plague* lọ larin wa ni *Inoculation* tabi Ibupa Alabẹrẹ to yatọ si *Vaccination* tabi ibupa ti olode. Ọfẹ ni awọn Dokita nbu u fun ẹnikẹni, ṣugbọn a gbọ pe Ijọba yio san owo fun wọn lori apa ẹnikọkan ti nwọn ba fi abẹrẹ gun. Egbogi ti nwọn nfi abẹrẹ rọ si enia lara yi lati apa, dabi egbogi ajẹsara tabi igbati a sin gbẹrẹ apedi. Sibẹsibẹ a mọ ọpọlọpọ enia to nsa fun *Inoculation* tabi Ipupa yi, a ko si le ba wọn wi pupọ titi a o fi la iyatọ to wa larin *Inoculation* nitori Ilẹgbona, eyiti o lodi si onn Gẹsi nisisinyi, ati *Inoculation* nitori arun *Bubonic Plague* ye wọn daradara.

Ki a to bẹrẹ Ibupa ti a npe ni *Vaccination* to dabi ajẹsara tabi ẹrọ Ṣọpọnna ni ilu Oyinbo Gẹsi ni ọdun Kẹrindiladoje ọhun, A.D. 1798 lati ọwọ Dokita kan ti orukọ rẹ njẹ Jenner, iru ibupa ti a nṣe titi di oni, obnirin ọlọla kan ti a npe ni Lady Montagu, ọmọ *Duke of Kingston,* ti o ba ọkọ rẹ Charles Montagu, *Earl of Halifax* lọ si ilu Tatanbulu ni Turkey nibiti o nṣe aṣoju Gẹsi, Obinrin yi, Lady Montagu lo ko aṣa ibupa ti a npe ni *Inoculation nitori Ilẹgbona wọ ilu Gẹsi.*

Ki obinrin ọlọla yi to ko Ibupa *Inoculation* de ilu Gẹsi lati ilu Tatanbulu, Olode jẹ ajakalẹ arun to le yọ Oyinbo lẹnu nigbagbogbo, o si npa nwọn ni apafon bi ọmọde meji nṣire.

Ẹniti nwọn ba ṣe *Inoculation* yi fun dabi ẹniti "ọba ti kọ" lẹkan fẹrẹ ti, to ba si kọlu u ni igbakeji, *Inoculation* ajẹsara ti o jẹ ṣiwaju, yio bu ipa amodi na ku.

Ṣugbọn nigbati obirin ọlọla yi bẹrẹ *Inoculation* rẹ, gbogbo ilu gba a bi eṣinṣin gba igba ọti; girigiri ni ẹsẹ si nwọ lọdọ rẹ.

Laipẹ, ika lati ọwọ ilẹ gbona ndinku. Sugbọn ewu nla nla to farahan lẹhin na ni pe, *Inoculation* yi jẹ ki ajakalẹ arun ilẹgbona tubọ pọ, pupọ si i, ni ilu Gẹsi ju bi o ti mọ ri lọ.

Bi igbati awọn Onisọpọnna nle olode l'oro nilu oke, bẹ gẹgẹ ni *Inoculation* Lady Montagu ṣe. Eyi si ba Ijọba Gẹsi lẹru to bẹ ẹ gẹ, ti nwọn fi ṣe ofin pe *a ko gbọdọ tun ṣe Inoculation tabi igunpa Alabẹrẹ nitori Ilẹgbona fun ẹnikẹni mọ; nigbati o ṣe pe egbogi na ti nwọn jẹ ko ṣiṣẹ apedi tun pada di agbejaedi.*

*Inoculation* tun ilẹgbona ti ko ba Gẹsi lara mu yi ni pataki egbogi iṣọra ti ara Tatanbulu nlo fun Ṣọpọnna; eyi tun jẹri si ọrọ ti a sọ siwaju pe "onjẹ ẹnikan le jẹ majele fun ẹnikeji."

Oṣu *August* to kọja yi ni nwọn ṣẹṣẹ ṣe egbogi *Inoculation* tabi Ibupa Alabẹrẹ to wa ni Eko yi ni ilu Oyinbo ki o to ba ọkọ *Abinsi* de, awa si ro ninu wa pe *Inoculation* ti Ijọba nṣe pẹlu awọn Dokita fun wa yi, yatọ patapata si irufẹ *Inoculation* ti Lady Montugu, ati pe ko ni wu nkan miran silẹ. Njẹ, bi ero wa yi ba tọ suna, ki Ijọba kiu wa lẹhin bi bẹkọ, ki nwọn da *Inoculation* duro; nitori gbo-

gbo agbagba ilu ti pejọ lẹkan ri, nwọn ko ri ẹbọ abamọ ṣe.

A o si tun bẹ Ijọba pupọ ki o sọ ohun mẹta fun wa :—

Ekini :—Bawo tabi *how long* ni Iṣọra *Inoculation* ti le pẹ to lara enia ?

Ekeji :—A ha tun le ko ẹniti nwọn ba ti ṣe *Inoculation* si l'apa lẹkan, lẹmeji tabi lẹmẹta lọ si Ikoyi tabi Abẹkun mọ, bi ẹnikẹni ba tilẹ ku ni ile tabi adugbo rẹ ?

Ẹkẹta :—Ijọba yio ha tun la oku ẹnikẹni to ba ku wo lati mọ aisan ti o pa a, lẹhin ti a ti ṣe *Inoculation* si i l'apa tan ?

Ibere pataki nla mẹta ni eyi, a si nreti idahun won ! Inu wa yio si dun lati gbọ pe olukuluku ẹniti o nka iwe yi lo ni itara lati gbọ esi idahun Ijọba si ibere wa nwọnyi ! ṣugbọn ki Ijọba to fesi, olukoluku enia le ma wadi ọrọ nwọnyi lẹnu Dokita to nṣe *Inoculation* fun l'adugbo, bi Dokita na ba si wipe on ko le dahun, ẹ jọwọ sọ fun ki o bere lọwọ Ijọba fun nyin, nitori ki ẹ le mọ gbogbo anfani ti ẹ le ri ninu Ibupa Alabẹrẹ tabi *Inoculation*.

## IFI ỌKAN TAN ARA ẸNI.

Nigbati ọrọ apa bibu de ilẹ, Ijọba fi ọkan tan awọn Dokita wa lati ma bu u fun enia ; njẹ bi eyi ba ri bẹ ẹ, (1) bawo ni nwọn ṣe nṣe iyemeji si iwe ẹri aisan ti nwọn ba wipe o ṣe oniko iku ẹnikan.

Bi Ijọba ko ba le fi ọkan tan awọn Dokita wa patapata awọn Dokita to gba oye bakanna bi awọn papa, (2) bawo ni nwọn ṣe le ni ireti pe awọn Dokita ti wa yio fi ọkan tan awọn Dokita ti Ijọba patapata ? Tabi bi ariyanjiyan ba nwa nigbagbogbo larin Dokita ti wa pẹlu Dokita olutọju ilu nipa iku to pa alaisan, (3) bawo ni awa ara ilu ṣe le fi ọkan tan ẹnikẹni ninu Dokita Ọba ati Dokita ti Ilu nigbati awọn mejeji nhuwa to jọ alaifi ọkan tan ara wọn si iṣẹ ara wọn ?

It takes two to make a bargain ; and as courtesy begets courtesy, so should confidence beget confidence. Whatever the authorities may say to the contrary, it really does seem in our opinion that *post mortem investigation in all cases of death duly certified by medical practitioners in attendance implies want of confidence in the skill of the medical officers concerned and involves to some extent, an aspersion on his diagnosis.*

A dupẹ pupọ lọwọ Ijọba fun gbogbo ajo ati wahala wọn lori wa, Oluwa ko ran nwọn lọwọ, ki o si jẹ ki ọwọ wọn ran ohun ti nwọn dawọle yi lati le arun *Bubonic Plague* kuro ni ilu.

Ẹnyin ara ilu, ẹ maṣe foya. Baba mimọ, yio gba wa lọwọ agbako aiye o.

Emi ni tiyin nitotọ,
ATARI AJANAKU.

## BABA WA TI A NWI, BABA WA DE !

O dabi ẹnipe a gbọ fẹnrẹn nibi kan pe Fọto tabi aworan HERBERT MACAULAY, ESQ., C.E., Kinniun onibudo de fun tita.

Bẹni tabi bẹkọ, ogbẹni Oluyẹle Bright ? Jọwọ jẹ ki a tete mọ, nitori ọpọlọpọ enia lo ti nyọ wa lẹnu pe ongbẹ aworan ẹni nla wa yi ngbẹ nwọn lati rà.

**Bargain in Buying.**

One Second-hand Motor Cycle
**"Sunbeam"**
*As good as new ; all parts complete.*
For sale ; apply to the EDITOR.

## ẸNIKEJI,

Aṣọ oke to yanju mbẹ l'ọdọ Iya Afin Saamọta Ikẹ Ọlọrun fun tita, ọpọku ọyọku ni owo wọn, lọ bere ni 3, St. John *Street*, l'Eko, leti ile Johnson Agbẹjọro.

**Springs ! Springs !! Gramophone Springs !!!**

ALSO

**Isolated Bottles ; Vaccum Flasks.**

Messrs. Remi Macarthy & Sons, of 5, Taiwo Street, Lagos, has just received a consignment of Springs adapted either for English or German Gramophones. Also (Thermos Bottle) Vaccum Flasks to keep water hot for 24 hours. The Springs and Flasks are sold at very moderate prices. Come and pick yours ere the Stock exhausted. The Flasks are assorted sizes and bodies.

**H. S. Freeman**

Photographer-in-Chief to His Excellency the Governor of Nigeria.

Dealer in all kinds of Photographic Materials

**Films, Post Cards, Views etc., etc, on hand.**

"Also films undertaken for development."

Satisfaction Guaranteed.

*Office* :—106, TOKUNBỌ STREET, LAGOS.

*Telegraphic Address* :—"**FREEDE**" **LAGOS.**

P. O. Box 405.

**J. C. VAUGHAN**

Ti Ile-Oja Sheffield ni Ita Kakawa ati Ile-Oja *Excelsior* " ni Ita Agarawu, ni oniruru awọn ohun ikọle fun tita ni owo ọpọku-ọyọku.

O ti nṣowo Irin Iṣẹ lorişirişi lati adọta ọdun ehin titi di oni.

ATARI AJANAKU ni ỌGBẸNI na jẹ ninu awọn onişowo Irin Iṣẹ ni ilu Nigeria.

ỌKỌ tita wa ni owo po ọ.

## Ero ya wa ra

ADEBOYE ṢOLANKẸ Onişowo Gbabiọgẹdẹ " nta Panu-kikọle ati kikanko, Iṣo lorişirişi, Kọkọrọ (Işika) t'ilẹkun ti t'apoti lorişirişi, Atupa fifalọwọ, Simẹnti, Oda lorişirişi ati Epo-ọda, Fikifiki, Okun ẹrọ, ti Ọşan, ati Pakun ti Awo-ẹja lorişirişi, Awo ti awọn Aganyin fi nko Ẹja-şawa, Pokun ati Ẹja Abọmafọ, ni Ṣọbu rẹ ni No. 4, Idunmagbo Street, (l'ebute Olowu) ati ni No. 19, Moloney Bridge Street, (l'Anikantamọ) l'Eko.

O nta Iworo (Golu) ati Fadaka-tutu ati in-işẹ Agbẹdẹ Iworo ati Fadaka.

Owo Ọja rẹ fanimọra. Ẹ lọ ra tiyin nibẹ

On si ni aşoju awọn ẹgbẹ Oyinbo onişowo o njẹ Arnold Whitehead Ltd. to wa n Manchester (Ni'lu Oyinbo) to si nranşẹ orişi-rişi ọja fun-ni lat'ọdọ wọn ni Eko ati agbegbe rẹ. Lọ ş'abere ẹhin ọrọ nipa owo yi lọwọ rẹ ni Ṣabu rẹ tabi ki o kọwe ranşẹ si ki o fi ṣọwọ sinu apoti ikọwe si t'Ọba P.O. Box No. 796, Eko, Nigeria.

Ẹ WA WO O.

Ọgbẹni E. A. Olemọ ti Ile Iṣẹ Oluwa, ni 73, Ọdunfa Street, (Anikantamọ) bẹrẹ iṣẹ agborun titunşe ti baba rẹ nisisiyi. Ojo eşe ti iwọ ati obinrin rẹ ma nsaba ju agborun nyin ti o ba bajẹ nu, Kai! Ọgbẹni kan mbẹ ni adugbo mi ti o mọ iṣẹ agborun nişişe lọpọlọpọ. Pọ lowo rẹ.

## Sabu Ajisefinni.

Gbakan-nşubu orişirişi Ọti *Beer* to jire wa fun tita ni Ṣabu Ibukun Oluwa, Ṣabu ti Mrs. A. Labinjọ ni No. 28, *Luther Street*, leti Mọşalaşi Olosun. Sarotu kekeke (*Cigarettes*) si nbẹ nibẹ bi tẹdi. Awọn *Lozenges* ati *Peppermint* lila, papa lakoko oworẹ yi ko şe fọworọ sẹhin. Gbogbo awọn ọja Ṣabu na lo nşeju si ni, pe kami, kami, kami.

Ọrẹ, sure tete lọ ra tirẹ nibẹ.
Kai! afara ni'ja Ẹkun.

**Cable Address :—**
"Steinafrik" HAMBURG
**E. H. STEIN & Co.**
HAMBURG, Neurwall 16/18.
Hildebrandhaus.
*AFRICAN MERCHANTS.*

***ALL INDENTS EXECUTED.***
for
English and Continental Goods
and
PRODUCE
Sold on Best Terms.

**Produce to Europe covered by Floating Marine Insurance Policy.**
*P. O. Box No. 505.*

Agent in Lagos :—
**Mr. Karimu Kotun**
3, Dosunmu Street.

**Ruby Plates! Ruby Plates!! Ruby Plates!!!**

BOON TO GOLDSMITHS

*Just arrived.*

Call at once and make your choice from :—

Duro Thomas,
55, Massey Street, Lagos.




*Reduced 3/- each.*

ACCESSORY AND PARTS

**For Bicycles For Motors For Gramophones**

*ASK FROM*

KADUNA STORES,

79, and 81, Odunfa Street, Lagos

*Near the palatial building of the late Mr. A. W. Thomas.*

And also expert in repairing all.

S. ADE CLAY.

---

Ọgbẹni T. A. Ẹrinoṣo jẹ Ojulowo Onisowo. O nfi ọja ranṣẹ, o nta ọja, o si nra ọja, o jẹ Onisowo patiki ninu Ekurọ Epo, ati orisirisi Ọja miran. Ọgbẹni na si tun jẹ ẹniti o gba iwe ati ma ta Ilẹ, Ile tabi Oko.

Ẹ lọ fi Ọja nyin fun u ni :—

19, Opopo Tinubu,

Tabi ki ẹ kọwe si ni :—P.O. Box 242,

Eko.

---

## T. A. Erinosho,

*Forwarding, Shipping, Buying, Selling and Commission Agent, Land and Estate Agent, Produce Merchant, Licensed Auctioneer & Valuer.*

19, Tinubu Street, P.O. Box, 242,
Lagos, Nigeria.

---

## JACOB AJAYI,

*General Woollen Trader,*

has on hand Woollens in endless variet[y] at 50, Dosunmu Street, Lagos, a[...]

***Prices to suit everybody.***

*Call now, fortune awaits you.*

---

ILU ẸPẸ KO KERE L'AWO, ẸIYẸ O BA LO GE.

Ọgbẹni S. A. Ọ. Macaulay ti No. 8 Opopo nla l'Eko nbi ṣẹṣẹ si Ile Egbogi ẹ kẹriri kan si eti Ebute l'Ẹpẹ.

Ile Egbogi na ko jina si Ile-Ọja [...]wo Oyinbo Onisowo John Holt.

Ọgbẹni yi ni Ajaloleru Egbogi ni Sabi na, eyiti ki foju arunkarun ba'lẹ gẹre ti ba ti lo wọn.

Ẹ wa dan a wo : bẹ lẹ o ba.

Ọpọku-ọyọku ni owo tita wọn.

---

B. A. ỌLA SILVA,

**Certificated Typewriter Mechanic**

*5 years Mechanical experience Marine Work Shop.*

Undertakes Repairs of Typewriters, &c., at moderate charges.

*Business Place :*

30, DOHERTY STREET, LAGOS.

**A Trial Solicited.**

---

**Ile Ita Egbogi ti Macaulay.**

88, BROAD STREET.

Wabiwọsi orisirisi Egbogi lo ṣẹṣẹ de fun wa ni tita : awọn bi :—ogun Egbo orisirisi ogun Ẹda, ogun arun aṣiri, ogun Arẹmọ, ogun Onigbameji, ogun Aran orisirisi, ogun Lakuregbe, ati awọn ogun miran ti a ko le mã to lẹsẹsẹ.

Ọpọku-ọyọku ni owo wọn, nwọn si jẹ bi idan.

Ọrẹ, ẹ lọ dan awọn Ogun wonyi wo nib[i] ti a gbe nta wọn.

---

PRINTED AT "TIKA-TORE" PRINTING WORKS, 20, MARKET STREET, LAGOS, AND PUBLISHED BY ADEOYE DENIGA AT 24, WILLIAMS STREET, LAGOS, WRITER AND LECTURER.